daada ni iwa daada, ẹṣẹ ni nkan ti nlọ ti mbọ ninu igbaaya rẹ, ti kò sì wù ọ ki awọn eniyan mọn

Lati ọdọ An-nawwaas ọmọ Sim'aan al-ansaariy - ki Ọlọhun yọnu si i - o sọ pé: Mo beere lọwọ Anọbi (ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ máa ba a) nípa iṣẹ daada ati iwa ẹṣẹ, lo bá sọ pé: "daada ni iwa daada, ẹṣẹ ni nkan ti nlọ ti mbọ ninu igbaaya rẹ, ti kò sì wù ọ ki awọn eniyan mọn ".

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Wọ́n bi Anọbi (ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ máa ba a) nípa iṣẹ daada ati iwa ẹṣẹ, ni o ba daun pe: Èyí tó tóbi jù nínú iṣẹ daada ni iwa rere pẹlu Ọlọhun láti ara ìbẹrù Rẹ, ati pẹlu awọn ẹda pẹlu imaa gbé àìda mọra, ìbínú niwọnba, itujuka, ọrọ ti o da lẹnu, ida ẹbi pọ, itẹle aṣẹ Ọlọhun, iṣe pẹlẹ, iṣe daada, ibani lo lọna to da, àti ibarinpọ tó da. Ṣugbọn ẹṣẹ oun ni nkan ti nlọ ti mbọ ninu ìgbààyà nínú àwọn iruju ati seyi sòún ọkàn láì sí isipaya igbaaya fún un, ti iyemeji nipa rẹ ati ìbẹrù nípa pe se ẹṣẹ ni tabi kii se ẹṣẹ ti kosi fẹ lati se afihan pe aida ni si awọn ojulowo ati awọn ti wọn pe leniyan, nitoripe adamọ ni pé ẹmi fẹ lati jẹ ki awọn ènìyàn rí daada rẹ, ti kò bá fé kí awọn eniyan ri awọn apákan iṣẹ rẹ, a jasipe iṣẹ naa kosi oore níbẹ.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/4308